# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà.

**Oṣù Kẹfà, Ọdún 2026**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KẸFÀ, ỌDÚN 2026

1. **Orísun igbàlà kíkún! Orísun igbàlà kíkún!**

Sí sílẹ̀ fún gbogbo wa,
Lát'ỌdỌ Olùgbàlà wà,
Ló nṣàn yí gbogb'ayé ká;
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

2. Ìran ológo li èyí

Ìsun ìwẹ̀nùmọ́ nṣàn,
Ó nwẹ gbogbo abàwọ́n nù,
Ti ìdálẹ́bi ẹsẹ̀,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ẹ̀jẹ̀ tí nwẹ̀ mọ́ láúláú.

3. Ìsun ijìnlẹ̀ ìfẹ́ Rẹ

Nṣàn ní inú ọkàn wa;
Ó nwẹ gbogbo erò aìmọ́,
K'a lè wà láílàbàwọ́n,
Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

4. Ìsun iyè aìnìpẹ̀kùn,

Láti ọ̀run nṣàn sí wa,
Ọlọ́run dàpọ̀ pẹ̀lú wa,
Idàpọ̀ t'ó dùn jùlọ;

Ó nṣàn síbẹ̀,
Ìsun igbàlà kíkún.

5. Àníyàn àti ìyèméjì, òkùnkùn òn ‘bànújẹ́,
Ẹ̀rù àti ẹkún kì íṣe t’èmi mọ́,
‘Gbàgbọ́ kò mọ òkùnkùn ọ̀la,
Tor’Ólúgbàlà mi ti lọ síwájú,
Ìsun ìgbàlà kíkún, ó kún títí láíláí

**1. Ọlọ́run t’Ó mú Ísráẹ́lì la òkun já.**
Tí Ó sì gbà wọ́n kúrò lí oko ẹrú,
Tí Ó rọ̀’jò ónjẹ sílẹ̀ láti ọ̀run,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

**Ègbè**
Ọ̀kan ná lónì, ọ̀kan ná lónì,
B’ákokò tí Ó sin Ísráẹ́lì la òkun;
Ọmọ Rẹ̀ ní un ó jẹ̀, ‘torí ọ̀rọ̀ Rẹ́ sọ
Pé, ọ̀kan ná nì Ọlọ́run
Ìyanu lónì.

2. Ọlọ́run t’Ó gba Dáníẹ́lì lọ́wọ́ Kinìún,
T’Ó sì yọ àwọn mẹ́ta n’nú iná’léru,
Ẹni tí àwọn ìràwọ̀ ngbà Tirẹ̀ gbọ́,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

3. Ọlọ́run t’Ó f’ọ̀rọ̀ Rẹ̀ d’áfẹ́fẹ́ dúró,

T’Ó sì nsọ ‘bànújẹ́ òní d’ayọ̀ lọ́la,
Ẹni tí Ó yí òkúta ‘bojì kúrò,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

4. Ọlọ́run t’Ó wọ itànná ìgbẹ́ l’áṣọ,
Ẹni t’Ó mú omi ṣàn n’íyàngbẹ́ ilẹ̀,
Tí Ó wẹ ẹlẹ́ṣẹ̀ mọ́ nínú èrí rẹ,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Mo pàṣẹ nípa àṣẹ ọ̀run, gbogbo ayọ̀ ọ̀tá lórí ayànmọ́ mi yóò tapadà lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Ìkórajọpọ̀ àwọn àgbà ìkà tí ó fẹ́ dójúti ayànmọ́ mi yóò wólùlẹ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo agbára òkùnkùn tó n pète-pèrò láti ṣe ìdíwọ́ sí ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìfarahàn ayànmọ́ mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára ìkà tí wọ́n yàn láti mú ìlọra bá ìtẹ̀síwájú mi yóò dópin lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Àsọkágbá ibi fún ayé mi yóò kú nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ọwọ́ ìkà tó n ṣiṣẹ́ láti jẹ́ kí n dìde, kí n tún ṣubú padà, òpin rẹ ti dé, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára búburú ilé bàbá mi, tó n dúró láti fàmíwálẹ̀ ní bèbè àtitàn mi, agbára Ọlọ́run Èlíjàh yóò dójútì ọ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**Jòhánnù 10:10** Olè kì íwa bíkòṣe láti jalè, àti láti pa, àti láti parun: èmi wá kí nwọ́n lè ní ìyè, àní kí nwọn lè ní i lọ́pọ̀lọpọ̀.

**Rómù 8:37:** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nkan wọ̀nyí àwá ju ẹnití ó ṣẹ́gun lọ nípa ẹnití ó fẹ wa.

**Sekaríàh 4:6** Ó sì dáhùn, ó sì wí fún mi pé, Èyí ni ọ̀rọ̀ Olúwa sí Serubbábélì wípé, kì íṣe nípa ipá, kì íṣe nípa agbára, bíkòṣe nípa Ẹ̀mí mi, Olúwa àwọn ọmọ-ogun wí.

**Lúkù 10:19** Kíyèsì i, èmi fún nyín lí àṣẹ láti tẹ ejò àti àkékè mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀tá: ko sì sí ohunkan bí ó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa-nyín-lára.

**1 Kọ́ríntì 15:57** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run Ẹnití Ó fi ìṣẹ́gun fún wa nípa Olúwa wa Jésù Krístì.

**Jòhánnù 16:33** Nkan wọ̀nyí ni mo ti sọ fún nyín tẹ́lẹ̀, kí ẹ̀nyin kí ó lè ní àláfíà nínú mi. Nínú ayé, ẹ̀nyin ó nì ìpọ́njú; ṣùgbọ́n ẹ túјúká; mo ti ṣẹ́gun ayé.

**2 Tẹssalóníkà 3:3** Ṣùgbọ́n olódodo li Olúwa, Ẹnití yóò fi ẹsẹ̀ nyín múlẹ̀, tí yóò sì pa nyín mọ́ kúrò nínú ibi.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ètò ìkà ìyówù tí wọ́n ṣe láti f'òpin sí ayànmọ́ mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ètò itìjú fún ayé mi, tapadà, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ọwọ́ ìkà tí wọ́n yàn láti dènà ìlọsíwájú mi, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
6. Ibi ilé bàbá mi kòní mú ayànmọ́ mi ní ìgbèkùn, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ìwà-ìkà ilé bàbá mi, tó lòdì sí ayànmọ́ ológo mi, èmi kì íṣe èrò rẹ, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.